## Asayan Oro

Ewurę wo alop... be ki o ku. Awodi wo igbin korọ, Kini ẹiyẹ oko yio fi Igbin ṣe ? Ori l'o nise ẹda l'a yanmọ.

# ELETI OFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

## Akiy i Pataki

A fiwe ... ṣe ikede si awọn Aṣ... iwe irohin Eleti-Ofe kak... agbaiye wipe, ẹnikẹni ti o ba fi owo ti o ti jẹ r... ṣe si wa, ... o pe lejọ, ako... ni fi iwe irohin ranṣẹ si ... abẹ mọ.

VOL. XI No. 639. LAGOS, SATURDAY, AUGUST 29 - SEPTEMBER 4, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)


# Sangba Fo! Oba Ilorin Ko Ri Ile Wo Nilu Kaduna

KADUNA. Irohin na yaoi lẹnu lati gbọ wipe ile ibiti ọba Ilọrin ma ndo si nilu Kaduna nigba ti o ba wa si ipade Lọbaloba ni awọn ọmọ onile kọ fun Sulu Gambari wipe, ko si aye ti yio wọ si nitoripe ile na Zaki Abdul Kadiri, Ologbe ọba Ilọrin lo ni, owo ara rẹ lo si fi ra, awọn ko gba wipe ki Sulu Gambari wọ sibẹ.

Nigbati Sulu Gambari ko ri ile ti yio wọ si, o ni lati ma ya otutu ilẹ Hausa, awọn ẹmẹwa rẹ si wa ile ti ọba yio gbe lọ si igboro.

Bi nwọn ti nwa ile kiri, ni nwọn ri ile kan eyiti nwọn ṣẹṣẹ kọ tan, ṣugbọn ti awọn Kapinta si nṣe iṣẹ ninu rẹ. Onile na bẹ ... kan Kapinta loju ki o tete yara pari lẹkun, ki o si fi window si.

## Oloye S. L. Akintola



Ninu ikede ti ẹgbẹ Afẹnifere se ni Isalẹgangan ni ojo 27th oṣu August 1959 fun ti ipalẹmọ ọjọ idibo sinu igbimọ Lagos Town Council, o sọ wipe Mọto Akero (Bus) ti di gbẹfẹ fun gbogbo enia.

Agbọ wipe Ogbeni J. N. Zarpas ngbero lati pada lọ si ilu rẹ ni ọdun 1960, nitorina gbogbo awọn mọto rẹ ti o fi nko awọn ero lọ si Idi-Oro Yaba Hughes Avenue, Ajegunlẹ ati Apapa ni Lagos Municipal ra lọwọ rẹ ni £100,000. Nwon si san idaji owo yi ni asansilẹ fun J. N. Zarpas.

Nigbati awon Municipal fi awon moto na ṣiṣẹ fun Ọdun kan, nigbati nwon ṣiro owo ti nwon pa larin odun kan na lẹhin ti won yo £100,000 iye owo ti won ra gbogbo moto na tan, erẹ ti nwon jẹ lori rẹ jẹ £160,000. Ka yin ọlọdun logo.

## ỌBA OKE ỌNA BA ARA IBARA SỌRỌ.

ABẸOKUTA. Ọba Osbile ba awon ara Ibara ni agbegbe Ẹgbado soro wipe ki olukuluku ẹniti o ba ṣi ni gbese owo ori lọrun ki o lọ san, nigbati nwon ba san gbese na tan, ki nwon duro ki nwon ma reti ohun ti ijọba Iwọ-orun yio ṣe.

Iye awon enia ti o mba sọrọ na to ẹdẹgbata enia ni arin oja orilẹ Ibara. Awọn ara ilu Ibara lo kọ oja na funra won.

Ọba fi ye won wipe, irẹpọ ati igl orọ si ara ẹni lẹnu si enia fi nna oja. O so fun won wipe idi rẹ ti on ṣe mba won sọrọ yi ni pe awon lo kowe si Olotu Ilera wipe ki o wa kọ isọ fun won, ṣugbon bi enia ko ba ni owo lọwọ ko le daba ohun kan.

Eyi ni idi rẹ ti mo ṣe so fun nyin lakọkọ, owo ori ti Ijọba nilati gba ni leyi koiti pe, nitorina, ẹniti owo ori ba si mbẹ lọrun rẹ, ki o tete lọ san.

## ỌNA MỌTO ILU ỌJỌ TO MOJU SI.

A ti nsọ nipa ọna moto ilu Ọjọ yi ti pẹ, a gbo wipe ni 1954 Ijọba Iwọ-orun fi ọkẹ meji ponun lelẹ wipe ki nwon fi ẹgba a mẹdogun tun ilu Egun ati Awori ṣe, ki nwon si fi ẹgbaa marun la oju ọna mọto, bakanna ni ijọba tun ṣe lọdun 1955.

Awon ti o mbẹ larin Ajegunlẹ ati Ọjọ woye wipe ki Ijọba bẹrẹ ọna mọto na, ti nwon ko si pẹkẹ lu u, nwon ko ara won jọ, nwon si la oju ọna moto lati oja Ajegunlẹ ni Apapa si Ọja Ọjọ, busọ mewa.

Oju ọna ti nwon la na ni moto nrin titi di bi a ti nwi yi. Nisisiyi ọna ti moto na nrin ti fẹrẹ bajẹ, fun koto ati gegele ti agbara ojo ti da sibẹ.

Ijọba sọ pe Oloye C. D. Akran yio bẹ Ọja Ọjọ ati agbegbe rẹ wo, ati pe ko nṣe ilu Ọjọ ni kan ni moto na yio duro, yio gba ibẹ kọja lọ si Badagry ni, ti nwon o si ma pe ni Trunk "A" Road.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## Eje Lotito Ni Enia Le Fa Ojo bi ?

Olotu,

Jowo gba mi laye lati dahun si ibere oke yi ti a gbo ninu ero gbohun-gbohun ti awon fesi re wipe ko si Iru oro bayi ko dara lati ma gbo lenu awon enia wa wipe ko si, kini nje be?

Bi a ba so wipe ko si, a mba ilosiwaju ile Nigeria je nuni, Olorun fun enia lagbara lati fa Ojo enia le so fun o ni akoko ti orun nran wipe, ojo yio ro ki ojo na si ro.

Ni akoko kan a gbo wipe awon Oyinbo Agbe ni Moor Plantation se ikede wipe awon fe gba eniti o le fa ojo sinu ise oba. Ere ki a fa ojo tabi ki a fo ojo, ko ja mo ebun kan nile Yoruba. (Western Nigeria).

Ohun ti ko jeki nwon ri Olojo gba ni wipe apa ibiti nwon ba fe ki ojo na ro si ni ki o ro si, eyi ni awon enia ko le se. Bi okuta ojo na ba ti tobi si ni riro ojo na yio fi po.

Nitorina e mase so pe, enia ko le fa ojo. Ohun ti o si se ti o si jeki nwon se ipinnu pe enia ko le fa ojo ni wipe gbogbo awon ti o soro nibi ero na ko de ibikan ri, nwon ko si ti ri Oogun abenu-gongo ri.

## Aringba-Nraye Farakorin

EKO. Okunwarata enia kan ti oruko nje Nathaniel Obi ni a gbo wipe nigbati o nrin irin-kurin ni Yaba ni odomobinrin kan, ri ninu ogba ile aladugbo re ti o je oyinbo funfun, o si sewo n'gbati ko le se alaye arare ni omobinrin na ba buso, logan, jagun ti tari omo na lule ki o le salo sugbon omobinrin na somo ko jeki o raye lo.

Nibe ni aburo odomobinrin na ti gbo igbe egbon re o si sare wa, ni o ba egbon re mu arigi-d'enia na, n ; awon ba fa le olopa lowo Adajo fisi ewon osu meta fun esun iringbanraye.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN


# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### METERS

Tenders are invited from responsible factors for the supply, c.i.f. to Lagos, of 9,600 No - Single Phase, house service pattern, 10 Amp MCR Meters with fully insulated cases and cyclometer dials suitable for use in the tropics on a 230 Volts 50 cps System, to be delivered regularly in Twelve batches of 800 per month.

On payment of a deposite of £5, tender documents, comprising tender and specification of the contract may be obtained from the undersigned.

Tenders must state when the first batch of meters will be delivered in Lagos and the method of packing must be described.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential-Tender for the supply of Meters" and must be received at the Office of The Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, 13, Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos, not later than noon on Thursday 17th September, 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

**ARTHUR FAUL**
Secretary to the Corporation

19th August, 1959.





## ROGBODIYAN BE SILE NILE HAUSA

JOS. Agbo wipe awon enia bi egba enia lokunrin ati lobinrin lo sopanpa lo fi idi ti si ile ise Ijoba ibile nwon si fi ijoye kan ti nwon npe ni Rwang Pam sun pe ayafi ki Ijoba ro o loye gbogbo won si ko ofa ati orun dani.

Ijoba ile Hausa yara fi moto ko awon olopa lati Sokoto, Jos, Argungu titi awon olopa fi de ibe awon enia na ko mira. Olopa pase fun won pe ki nwon tuka, nwon si ko lati tuka, ni nwon ba yinbon apamoteku si arin won, ni gbogbo won ba tuka o di bi o ko lo yago fun mi. Sugbon owo olopa te enia medogun, gbogbo won ni Alikali agba da si ewon.

Lejo yi kanna ni awon ara ilu Argungu tun lo sopanpa sile Oba won, wipe awon ko fe mo ni oba. Bakanna ni, ni Sokoto nigbati awon egbe kan soko lu moto egbe Action Group.

Oba Sokoto ran awon alagogo re jade wipe enikeni ti o ba huwa ja-dukun ewon ni yio lo. Ki olukuluku so agbejo modi.




kan ni i y e awon enia ti o mbẹ nilu Ọtta, olukuluku awon ilu lo nsare tete fun ilosiwaju ilu won. Bi o ba si ngbọ wipe gbe, gbe, bi iwọ ko ba tete ba won gbe, ẹhinkule oluwarẹ ni nwọn o gbe ju si.

Gbogbo wa lo nfi oju sọna fun Ominira, ninu ile wo ni awon ara Ọtta yio ti yo ayo Ominira ? Ẹnyin igbimo Ọtta, ẹ fi eyi si ero.

Emini
Olu Jackson.

## KINI FA SABABI TI ORI ENIA FI NPA

Olotu,

gba mi laye lati dahun si ibere oke yi ti o jade lati inu ẹrọ-gbohun-gbohun eyiti ọpọ awọn enia gba wipe, ẹniti ori rẹ ba pa, o kan pa bẹ lasan ni.

Ohun ti mo fẹ fi ye awọn ọjọgbọn inu ẹrọ gbohun-gbohun na niyi. nitotọ ni „Ko si bi ọbẹ ti ṣe ori ti inaki ko se" Ṣugbọn ọgbọn olukul u k u j ẹ iyana ọtọtọ. Bi o ba ri ẹni ti ori rẹ pa, (1) o le di Olowo lehin wa ọla bi Ọlọrun ba fẹ (2) Bi ko ba ni ọgbọn o r i yio lọgbọn inu. Paripari rẹ ni pe oni lati ni ohun kan yala ni aṣiri ti ko han si gbogbo enia mo fi ju ẹlẹgbẹ rẹ lo, tabi lọna riran ti o han si ode fun enia ri, sugbọn ko nṣe bi ti omugọ gẹgẹbi ẹrọ na ti wi.

Ọkunrin kan wa nilu Eko ti wọn npe ni Professor Gidi gidi ti ori rẹ pa o si ti nse iṣẹ Post Master ri ni ilu Sapẹlẹ Nigbati o mbẹ ni Ṣango-odc lo gba oye Professor re. Nilẹ Yoruba, awọn apiri ko wọpọ ṣugbọn ni le Hausa ati nilu Oyinbo, pupọ ninu awọn to gba oye Professor, Lord, Millioneer, ati, awọn scien-tist jẹapari enia Ẹbun Ọlọrun ni, ko se fi ọgbọn ni

Kole Badaru

## Adajo Agba Tun Da Elejo Lebi

Ọkunrin Adajọ kan ti a gbọ wipe o ṣẹṣi fi moto rẹ pa ọga lebira kan nibiti o gbe nse iṣẹ ni Ọttọ. Awọn Olopa ba adajọ na ṣe ẹjọ niwaju adajọ kotu kekere. Adajọ da lẹbi, o ki o lọ san adọta Pounu si kotu.

Adajo ti o ṣẹṣi pania na so pe fun adọta Poun ti nwon ni ki on san na, rara! on ko jebi to be, ettorina on yio gbe ẹjọ na lo si Kotu Arotunro tabi Kotemilorun n i K o t u nla (Appeal).

Nigbati nwon tun ko s i e n u e j o n a a d a j o agba ri ẹjọ alasise na ko mọọ lo ba ni ki o lọ san adọta pọnun na.




## Asiko To Fun Ilu Otta Lati Ni Ile Egbe

Olotu,

Gbami laye lati ba awọn ara ilu Otta damọran wipe asiko ti to fun wọn lati ni ile awọn Ero (Hall) tabi ile ẹgbẹ (club House).

Pupọ [illegible] awọn ilu ti ko to Otta lo ti ni ile ero, eyiti ko ni ile ero ni ile ẹgbẹ. Boya, a le so wipe ninu iṣọwọ kan na ni Otta ati ilu Oshogbo nwọn je ọgba, [illegible] ti nwọn gba ninu Otta ni nwọn gba ni Oshogbo, ilu Oshogbo ni ile Ero (Town Hall) nwọn si tun nile ẹgbẹ

Kini ti ilu Ọtta ti je? Ọkẹ

Kẹrẹ o !

A ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7 Egerton Road Lagos

## N'tan So L'Offa Mojo, Nile Olalomi

ILỌRIN. A gbọ irohin kan ilu Offa wa wipe, gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ ilu Ilọrin bi ọba kan ba ṣẹṣẹ-jẹ yio rin gbogbo ilẹ ti o mbẹ ni abẹ aṣẹ rẹ wo.

Nigbati Malam Sulu Gambari, ọba ilu Ilọrin fi ọran gbogbo ilẹ ti o mbẹ ni abẹ Ijọba rẹ wo ti o de ilu Offa mọjọ, awọn ara ibẹ ti tara-tara yẹ ẹ si. Nigbati o ṣe ni awọn enia mẹrin kan mu iwe to ọba wa.

Ohun ti nwọn sọ sinu iwe na ni kukuru ni wipe, inu awọn dun si oye ti ọba naje, ṣugbọn awọn ko fẹ ọba ti awọn ara Ilọrin je fun wọn n torina awọn nfẹ ki nwọn da ọba Isioye pada wa s'ori oye ọba Ọffa.

Ọba Ilọrin wipe, mo gbọ gbogbo ohun ti ẹ wi ṣugbọn ẹnyin melo ni o kọ iwe yi ?. Awọn enia na dahun pe, nwọn pọ to ọgọrun enia; ọba dahun pe on ko gbagbọ wipe nwọn pọ to ọgọrun enia, bo ba si jẹbẹ nitotọ, on fẹ ri gbogbo wọn loni. Awọn enia na ṣkọ nwọn si bẹrẹ si wa ara wọn kakiri.

Nibiti nwọn ti nwa ara wọn kiri lọwọ ni ọba ti fi ẹrọ isọro sọrọ si Ilọrin wipe ki ogun awọn ọlọpa mu bọ wa ba on ni ilu Ọffa kiakia. Kia masa awọn ọlọpa na ti de, ọba si ti pari eto rẹ pẹlu wọn.

Nigbati aw'n enia na de nibiti nwọn gbe ṣe "Ranka-dede" fun oba lowo ni awon olopa bo won, o di bi o ko lọ, o yago fun mi. Ọlọpa ri iwon ogoji enia ninu won. Ọba Ilorin wa wa paṣẹ wipe, ki nwon ko lo pamo si Agbadamu titi on yio fi ti ajo de ki nwon to wa soro won.

# Ojo Gbogbo Ko L'odun



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Bassey ni akoko ti o nse idanrawo lati lo ba Davey Moore fi peki-ko peki, ni ilu Los Angeles ni Amerika, ṣugbọn igba ko nlọ bi orere. Ogun Bassey ṣẹpa. A ti gbọ owe Yoruba ti o wipe, ohun ti enia ba mo lamoju lo nsoni di ẹru. Jẹki Basey ma bo wa sile




## IYAN MU L'OMU ỌLỌMỌ SỌMỌ NU

Ọkunrin agbẹ kan wa ti o bi ọmọ meje, ọdun kọkan ni awọn ọmọ na fi ju ara wọn lọ. Eyi akobi omo ọdun mọkanla ya ṣungọmu pupọ abigbẹhin, ọmọ ọdun marun ni awọn enia fun ni orukọ yi, Akerele. Eyi ni oriki ti nwọn fi nki i - Akerele bi ewu, ọlẹ ko fi ara ija ya Anikangboja bi atupa'

Idi rẹ ti nwọn ṣe npe ni orukọ yi ni wipe, o jẹ ọmọ ti o gbọn, ti o ni suru, ti o si farabalẹ, ko fẹran ijakadi tabi jagidi-jagan, o si lọgbọn ninu ju gbogbo awọn aṣiwaju rẹ lọ.

Ni ọjọ kan iyan mu, mu, mu, o pa ọba Olomu, o pa igba ẹranko, o pa agbagba mẹfa. Ojo pata, pata, pata, bọ silẹ ọmọ adiẹ sare si i o he e mi, Ọmọde da epo iṣu nu si atitan, Alamu sare mọ boya on yio ri epo iṣu họ jẹ. Nigbati o de ibẹ ti ko ri nkokan họjẹ, o ni, ha! nigbati ọmọ gbọ, o ni gbami-gbami.

Iyan na mu tobẹ gẹ, ti o ọlọmọ ko fi mo omo rẹ. Ọkunrin agbẹ na wa pe iyawo re o wipe nitoto ni a bi mọ pupo omo bẹrẹ ati oṣi bẹrẹ ko suwon mo fẹ damoran kan. Nisis'y owo mbẹ ṣughon a ko ri onjẹ fi ra lati jẹ kanu. Nitorina jẹki a ko awon ọmode nwọnyi lo danu sinu igbo. Bi emi pẹlu rẹ ko ba ku ao bi omo miran.

Ni a tetekoṣe iya awọn omọ na ko gba lati ko awọn rẹ danu, lati igbana ni iya awọn ọmo na ti bẹre si ronu ti o si nkajo ṣugbon nigbati o ṣe o gba lati ko awon omo na danu, nitoripe omi lo danu akeregbe ko fọ.

Ni ọ'ọ ti nwon nso ọrọ yi. Akerele mbẹ nile, o si gbo gbogbo etẹ ti awon obi nwon ngbero le wọn lori.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ losẹ ti o mbo ẹo gbo gbogbo bi awon obi awon omo na ti ṣe lo da won nu sinu igbo ti nwon si bo si owo Iya Ajẹ.

# LAGOS RACE CLUB

An Extraordinary General Meeting of the Lagos Race Club will be held at the Members Enclosure, Race Course, on Friday, September 11, 1959 at 5. 30 p.m. Members should please note that admission will be by production of current badges only.

**Agenda :-**

1. Revision or Amendment of Club Rules.
2. Any other business.

C M NORMAN-WILLIAMS
Hon Secretary


# ELETI - OFE D'ARABA





**Wholesale Distributors:**

Badejo Stores, 5 Olorogun St., Lagos
Dayo Development Co., 161 Victoria St., Lagos
Jony Ola Fajumolu & Bros., 21 Balogun St. West, Lagos
Nwosu Bros. Stores, 24 Asa Rd., Aba
Ebele Egbunam Stores, 38 Church Road, Kano
Olasinboh Business Enterprise, P.O. Box 53, Kano
Ezenwaku Trading Stores, 48 Aggrey Road, Port Harcourt

PHILIPS (W.A.) LTD. P.M.B 2023 Lagos


## Awon Babalawo Dite Lati Gba Iyawo Orunmila

(Apa) 2

Lati ọwọ ẹṣọ

Lẹhin ti awọn Babalawo ti gbọ awipe, Orunmila ko mọ ibiti iyawo re gbe wa obinrin rẹ? Orunmila dahun pe, on fi le ọwọ Okunrin Gbalanja, orukọ ti a npe Ogun, Ogun ni yio ba on wa obinrin na, ko si mọ pe ninu imulẹ awọn Babalawo ni Orisa Ogun wa. O wa obinrin na lọ, o wa a bọ o ni on ko ri iyawo Orunmila.

Nwọn tun bere lọwọ Orunmila wipe, tani yio ba ọ wa iyawo re? Orunmila, ni, on fi ọrọ na le owo Ọkunrin Gbalaja bi ikọkun Orukọ ti a npe Orisa Oko. on nj yio ba mi wa obinrin na. Orisa oko tun wa obinrin na ni awati.

Nwon tun ni iwọ Ọrunmila tani yio ba o wa obinrin rẹ? Ọrunmila dahun wipe, Ololo Ori-a-gbele orukọ ti a pe ṣango ṣango ni yio ba mi wa obinrin na. Ọrunmila ko ni mi mọ pe ṣango papa wa ninu imule. Bẹni Orisa ṣango lọ, o wa obinrin na ni awati.

Bi ao ba dibo Kawo eni rere kọ ni nibo Kale ba mọ ibo ni didi. Otura-meji

Nwon tun ni iwọ Ọrunmila, tani yio ba ọ wa obinrin re? Orunmila dahun wipe, Ọknnrin Kukuruku-bi-iku orukọ ti a npe Eṣu on ni yio ba mi wa obinrin mi. Gẹgẹbi o si ti je wipe Eṣu papa na mbe ninu imulẹ, o wa obinrin Ọrunmila, o wa a ti Orin:- Ifa ko npurọ
Iyẹn iran awa o
Ifa ko ndale, ko npurọ

Nigbati Ọrunmila woye gẹgẹbi nkan na ti nlọ yi, ara fu u wipe, nwon ti doyi ka on, nigba na o wa woye lọ titi, o wipe bi iwaju ko ba ṣe lọ, ẹhin ni a npada si, asiko to fun on lati jewọ ile, nitoripe bi "Ako ba pa Iji han Iji, eru ko ni ba Iji". Nwon tun ni Iwọ Ọrunmila ta ni yio ba ọ wa obinrin re? O dahun pe, o ku Otura-meji.

Bẹni Otura-meji dahun pe "Yesireni" Eṣu si dahun pe, ṣe iwọ na ni nwon mba wi. Nigbana ni Otura-meji sọ wipe, njẹ bi o bajẹ wipe bi temi ni nwon ba nwi, kan, kan, kan ni ewe ina njo ọmọde wara-wara ni ọmode nti oko esisi bọ, ile ko gba a ọna ko gba niti aragba. Ibikibi to wu ki Onipupa wa loni, ewe agbe ko ma ba mi gbe, ọgọmọ ko yọ o wa, abẹrẹ olokun ndi ki sọnu

(1). Bi ao ba gba ibo
Ka wo eni rere ko ni nibo
Kale ba mo Ibo ni gbiga
A difa fun Ọrunmila
A ni ki o ru, imọ ọpẹ

(2). Ewe aragba, ata,
Ewe Agbe, abẹrẹ olokun nide Ọrunmila ẹbọ, o ru. O si pade iyawo ti o fẹse asa rẹ rin wọle.

## AWỌN TO DA ỌJA FUNRA WỌN F'ARAKORIN

ISẸYIN. Irohin kan wa wipe awọn mẹrin ninu awon igi lehin ọgba fun ẹgbẹ Alakukọ ti oruko won nje Abioye Ẹlẹyinpẹ, Makanju Ikalabu, Raji Ẹkẹrin, ati Raji Akanni ni nwon ṣe aiya gbangba duro niwaju ọmọ ẹgbẹ Alakukọ lati lọ da oja tiwon ni iyana ọtọ nibiti o je wipe ọmọ ẹgbe N C N. C. nkanṣoṣo ni yio ma na ọja nbẹ laigba aṣẹ Ijoba ki nwon to ṣe bẹ.

Ijoba mu awọn asiwaju mẹrin ti a daruko nwonyi lo si kotu Ijoba ibile nilu Ọyọ, ibẹ ni nwon ti ba ṣe ẹjọ, adajo da won lẹbi o ni ki ẹnikọkan le san Ogoji ponun, bi ko ba si ri ogoji san ki o lo si ẹwon oṣu mẹrin-mẹrin.

Bena ni awon enia mefa nwonyi Y. Adejuwon, S. Atada, O. Alele, R. Dosunmu Y. Oribobade ati Aminu ọmọ ẹgbe N. C. N. C ti nwon lo lu okan ninu awon ọmọ ẹgbẹ Afenifere ni abule Alaparun, lakoko idibo Adajọ da won lẹbi, eni ti o san owo kekere ninu won lo san Ponun mẹdọgbọn.

## Oloye Olumegbon Tako Ofin Ijoba Ibile Titun

EKO. Oloye Lamidi Kalfo ti o je okan ninu awon Ijoye Ibilẹ Eko so nipa ofin ti Ijoba ṣe lati fi fun oba Eko ni agbara fifini joye ati rironi loye, awon Ijoye ibilẹ Eko lodi si ofin nitoripe ko ba asa ibile mu rara.

Oloye Olumẹgbon so wipe lati igbati iwa ṣẹ ẹniti o ba jẹ Olori ni idile Ijoye kokan lo nyan Olori ebi lati fi joye idile won lehin na, ni nwon ma lo fi han oba. Pelupelu lilo fi han oba je asa isẹdale lasan ni.

Bi edekoyede ba bẹ silẹ larin oba ati Ijoye pata-pari nkan ti oba le se ni wipe, ki o da ijoye na duro wipe ki o maṣe tun wa si ose Iẹa mọ. Nitorina ofin ti Ijoba se Nipa oba lodi si aṣa isedalẹ.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

**STEP UP TRANSFORMERS FOR THE SMALL TOWNS DEVELOMENT PROGRAMME**

Tenders are invited for the supply, c.i.f. to Lagos, of 13 identical 11 K V 300 K V A Transformers.

On payment of a deposite of £5, tender documents, comprising tender form and specifications of the contract may be obtained from the Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, 13, Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential-Tender for the supply of Step-Up Transformers for the Small Towns Development Programme" and must be received at the Office of The Secretary not later than noon on Thursday 17th September, 1959. Tenders received in any other manner will not be considered.

On receipt of a bona fide tender, the £5 deposite will be refunded. The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

**ARTHUR FAUL**
Secretary to the Corporation

20th August, 1959.

### OLOYE AWOLỌWỌ LỌ KIRUN NI MỌṢALAṢI NLA



Ẹniti a nwo ninu aworanjyi si Olola Oloye Awolowo, ẹniti a gbo wipe o ti de silu Eko, ni ọjọ Jiẹo 28th osu August 1959.

lati wa lo josin fun Ọlorun ninu Mọṣalaṣi Jimo pẹlu awọn Musulumi Eko. Atun gbo pe yio tun lo josin ninu ile isin Alagogo ti ijo Bẹteli ni ojo osẹ ola. Lẹhin na ni a gbo pe yio bẹrẹ ikede fun idibo turẹ.

TREBLE "O" SYSTEM
Remarkable Football Pool System
Thousands Already Won.
Send 10/- For Complete System to :
S. O. S (EO) ROYAL EXCHANGE,
MANCHESTER

# AUGUST

24th to 31st x x x



# ATTRACTIONS

## Now In Full Swing

★ **MANS SHOP**

KERKO full sleeves DUTCH SHIRTS 20s
WOOLLEN TROUSERS 52/6d
ONLY 50 PAIRS pr.
Khaki Shorts 200 ONLY 8s 6d pr.
COTTON CORD TROUSERS 21s pr.

| SHOES | BEACH SANDALS | Cotton HANDKERCHIEFS |
|---|---|---|
| going at throw - away prices from 16/- pr. | from 4s 6d pr. | 10d each |

★ **children sec.** second floor

SOCKS x BIBS x SHIRTS x PYJAMAS
REDUCED to clear .... quantities are limited .... come early to pick the best

★ **Household**

GLASS TUMBLERS 5d Each | K.D.K. TABLE FANS for cool comfort £5 0 0d
CONTINENTAL STYLE TABLE and WALL LAMPS 25o/o to 50o/o off
ODDS & ENDS of CROCKERY reduced to rock - bottom prices to clear
FLASH - GUNS 15s FOR PHOTOGRAPHY
WE OPEN .... TODAY & MONDAY
SUPERMARKET 8.30 a.m. - 7.0.0 p.m. (no break) as usual
OTHER DEPARTMENTS 8.30 a.m.-12.30 p.m. & 2 p.m.-7 p.m.

101 BARGAINS IN OTHER DEPARTMENTS COME EARLY

Bhojsons

BHOJSONS STORES, OYINGBO, P. O. BOX 63 EB.

Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 78 Kosọkọ Street P.O. Box 467 Lagos, Phone 23370